Bibeli fun awon omode



# Okunrin ti oti odo Olorun wa

Ikosile gba owo: Edward Hughes
Ayaworan: Alastair Paterson; Byron Unger; Lazarus
Olu'lo: E. Frischbutter; Sarah S.
Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu
Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

BFC
PO Box 3
Winnipeg, MB R3C 2G1
Canada

©2020 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi, niwon igba ti o ko so di owo.

Li ojo kan ninu tempili, Alufa agba kan, ti nje Sakariah, nfi turari jona. Li ode, awon eniyan ngbadura. Lojiji, Sakariah beru.



Angeli kan to o wa. "Mase beru" owi fun. "Olorun ran mi. Iyawo re yio bi omokunrin kan. Pe oruko re ni Johannu. Yio kun fun Emi mimo lati inu oyun wa. Yio yi awon Eniyan mi pada si Olorun".



"Bawa s'oro, Sakariah." Oya awon eniyan towa lode lenu. Won ko mo wipe angeli Gabrieli t iwi fun Sakariah wipe ki yio le soro titi ojo ibi omo na nitoripe ko gba oro Olorun gbo. O ro wipe Iyawo re ti dagba ju eniti ole bi omo lo.



Ni Ile, Sakariah ko gbogbo ohun ti Angel wi fun. Oje iyalenu fun Elisabeti, Iyawo re. Won ti ngbadura lati ri omo bi. Nje ole sele bayii?





Laipe Elisabeti mo wipe omo nbo.  O fiyin Fun Olorun.  Li ojo kan, Ibatan Elisabeti, Maria, se abewo re.  Maria pelu loyun omo.



Nigbati Maria wole de, Ole omo so ninu Elisabeti. Elisabeti kun fun Emi mimo. Oni Idani loju wipe omo Maria gbodo je Jesu Kristi.  Lapapo, awon Ibinrin meji wonyi fiyin f'olorun pelu ayo.



Elisabeti bi omo gegebi
Ileri Olorun. “Pe oruko re
ni Sakariah, gegebi Baba re,”
awon Alufa lo so eyi. Sugbon
Sakariah ranti ase Olorun.
“Rara o! Johannu Li oruko
Omo na.” Nigbati Sakariah
ko awon oro yi sile, ahon
re si lati so’ro.
O fiyin fun
Olorun.



Nigbati Johannu dagba odabi Elija, Eniyan Olorun nla. Johannu so fun awon Eniyan wipe Olugbala nbo lati wa bukun fun won. Awon agba Ju korira Johannu nitoripe oni ki won "ronupiwada! Ki won mase da ese mo." Won ko fe gbo ohunkohun nipa ese won.

Awon miiran pe ni Johannu onitebomi nitori wipe o rin awon eniyan sinu omi ki won bale kedun fun ese won. Li ojo kan, Jesu to Johannu wa lati se iribomi. “Iwo loye ki ote mi bomi,” Johanu wi. Sugbon Jesu wi fun pe “Jeki ori be.” Johannu si ribomi.



Lehin iribomi Jesu, Johannu ri Emi mimo sokale s’ori Jesu ni rir eiye Adaba.  Eyi ni ami Olorun. Johannu mo wipe Jesu ni omo Olorun. Johannu pe Jesu li Odo-aguntan Olorun to mu ese araiye lo.



Johannu mu opolopo Eniyan wa si odo Olorun.  Sugbon Herodu, asebi ni, Mu Johannu osi fi sinu tubu.  "Kiise ohun toto lati gba aya arakunrin re, Herodiasi gegebi aya a re," Johannu wifun Herodu.  Herodu mo wipe otito li eyi je.  O mo wipe Iranse Olorun li Johannu nse, eni otito and eni mimo.  Sugbon ko fe dawo ese re duro.  Johannu pelu ko le dekun lati ma soro si ese bo tile je wipe afi sinu tubu.



Herodu ni ayeye ojo ibi nla. Omobinrin Herodiasi jo fun. Eyi te Herodu l'orun. Herodu se Ileri "Ole ni ohunkohun ti oba fe, titi de idaji Ijoba a mi".





"Kini ki n bere fun" Omobinrin na ronu.  Eni ibi Herodiasi, to korira Johannu so ohun ti yio bere.  Oje kayefi!

"Fi ori Johannu onitebomi si ori apete fun mi," omobinrin na wi fun Herodu.  Inu re baje nitori ileri re, sugbon ogberaga lati yi pada.
"Ge ori Johannu, ki o gbe wa", Herodu pase.
Awon omo ogun re gboran si lenu.



Pelu ibanuje okan, awon ore Johannu sin oku Johannu, iranse to gboju tosi je olooto. Ise iranse Johannu ti pari. Boya won mo wipe Jesu yoo tu won ninu, ninu ibanuje won.



Okunrin ti oti odo Olorun wa

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Maku ori kefa, Luku ori ikini ati iketa

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi 119:130

Opin

37

60

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo! Johannu ori keta ese kerindinlogun.